**ÌKÉDE KÓKÓ-Ọ̀RỌ̀ TI ỌDÚN 2012**

**Bẹ̀rẹ̀ Pẹ̀lu Àlàáfíà nínú Ilé lọ sórí Àlàáfíà ní Àgbáyé: Ẹ jẹ́ kí á tako ìṣesí-ológun, kí á sì Fi òpin sí Ìwà-ipá sí Obìnrin!**

Ipolongo Ọlọ́jọ́ mẹ́rìndínlógún ti 2012 yóò máa tẹ̀síwájú pẹ̀lú kókó-ọ̀rọ̀ kárí-ayé yìí: **Bẹ̀rẹ̀ Pẹ̀lu Àlàáfíà nínú Ilé lọ sórí Àlàáfíà ní Àgbáyé: Ẹ jẹ́ kí á tako ìṣesí-ológun, kí á sì fi òpin sí ìwà-ipá sí obìnrin!** Pẹ̀lú ìpolongo ti ọdún yìí, ó ti pé ọdún mẹ́ta tí a ti ń ṣe ìgbẹnusọ fún dídènà ìwà-ipá àti ìṣesí-ológun síni nítorí pé a jẹ́ obìnrin. Ibùdó àwọn Obìnrin fún Ipò Aṣaájú Lágbáyé, gẹ́gẹ́ bí alàmójútó ìpolongo náà káàkiri àgbáyé, kò dẹ́kun ìbáṣepọ̀ rẹ̀ pẹ̀lú àwọn àjọ olùkópa gbogbo láti jọ máa tako ìṣesí-ológun. Ohun tí ó fa èyí ni àwọn ìjábọ̀ tì wọ́n ń mú pada tọ̀ wá wá. A sì dìjọ ń tọpinpin àwọn àgbékalẹ̀ àwùjọ́ àti ti ọ̀rọ̀ ajé tí ń fi ààyè gba híhù ìwà-ipá sìni nítorí pé a jẹ́ obìnrin.

**Ìṣesí-ológun sì wá síbẹ̀ gẹ́gẹ́ bí oríṣun pàtàkì fún ìwà-ipá sí obìnrin.** Gẹ́gẹ́ bí ìlànà ìrònú ènìyàn tí ó ṣe àgbékalẹ̀ àṣà ìṣẹ̀rùbani, ìṣesí-ológun fàáyè gba lílo ìwà-ipá àti ti òǹrorò. Ò tùn fàáyè gba àwọn ológun láti máa lọ́wọ́ nínú ìpẹ̀tùsíjá àti ìgbéró àwọn òfin tó jẹmọ́ ọrọ̀-ajé àti ti ìṣèlú. **Ipa ìṣesí-ológun hàn gbaǹgba, ó sì ni ipá ńlá lórí àwọn nǹkan tí ó jẹmọ́ àmúṣọrọ̀, àṣà àti iṣe pẹ̀lú ìhùwàsí ní àwọn àwùjọ wa.** Ó jẹ́ àǹfààní fún lílo jàgídíjàgan ní oríṣiríṣi ọ̀nà láti fi agbára ọkùnrin hàn. Ó sì tún jẹ́ kí wọn gba pé ìwà-ipá gẹ́gẹ́ bí ọ̀nà tí ó rọrùn láti fi yanjú ìṣòro.
**Ìṣesí-ológun kìí sáábà ní àyọrísí rere fún ààbò àti ìpèsè-ààbò láwùjọ́ lápapọ̀, yálà fún obìnrin, ọmọdé àti ọkùnrin pẹ̀lú.** Ìṣesí-ológun ní ipá lórí ojú tí a fi ń wo obìnrin, ọkùnrin, ìdílé wa àti aládùúgbò ẹni. Ó tún kan ojú tí a fi ń wo àwọn ènìyàn àwùjọ wa ati àwọn ènìyàn orílẹ̀-èdè mìíràn kan.[1] Nǹkan wọ̀nyí bẹ̀rẹ̀ lórí ìfipábánilò lásìkò ogun àti rírà ọ̀pọ̀lọpọ̀ ìbọn ìseré fún àwọn ọmọdé.

Ní ọdún 2011, ikọ̀ àwọn akọ́ṣẹ́mọṣẹ́ àgbáyé fa kókó pàtakì márùn-ún jáde láti inú kókó-ọ̀rọ̀ kàrí-ayé wa. Àwọn ni ìwọ̀nyí: (i) ìwà-ipá oní-ìṣèlú sí àwọn obìnrin; (ii) kíkó àwọn nǹkan ìjagun kéékèèkéé wọlé yaǹturu àti ipa tí wọ́n ń kó nínú ìwà-ipá abẹ́lé; (iii) ìfipábánilò làsìkò ogun àti lẹ́yìn ogun; (iv) bí àwọn tí ń ṣiṣẹ́ fún ìjọba ṣe ń kópa nínú ìwà ọ̀daràn ìfipábánilò àti ìwà-ipá síni nítorí pé a jẹ́ obìnrin; àti (v) ipa tí àwọn obìnrin, àlàáfíà, àti àwọn ẹgbẹ́ ajàfẹ́tọ̀ọ́-ọmọnìyàn le kó nínú dídojúìjàkọ àjọṣepọ̀ tí ó wà láàrin ìṣesí-ológun àti ìwà-ipá sí obìnrin.

Pẹlú ìjábọ̀ láti ọ̀dọ̀ àwọn olùkópa nínú ìpolongo[2] ọdún 2011, Ìpolongo ọlọ́jọ́ mẹ́rìndínlógún ti ọdún yìí yóò tẹjúmọ́ mẹ́ta nínú àwọn kókó pàtàkì márùn-ún náà:

**1. Ìwà-ipá Láti ọwọ́ Àwọn Agbèfọ́ba:** Àwọn ìjọba àti agbèfọba máa ń lo ìwà-ipá láti mú ìlépa wọn nípa ìṣèlú wá sí ìmúṣẹ.  Wọ́n ń ṣe àmúlò ìṣesí-ológun gẹ́gẹ́ bí ohun tí wọ́n nílò fún ààbò orílẹ̀-èdè. Èyí ni ó sì máa ń mú wọn fọwọ́ sí ìwà-ipá àti ìkóniláyàjẹ bí ọ̀nà láti pèsè ààbo. Àwọn ènìyaǹ tí ó wà ní ipò àṣẹ gbà pé àṣà ìwà-ipá nípa ìṣesí-ológun fi ààyè gba awọn làti rúfin láìsí ẹni tí yóò bi wọ́n. Èyí ló fà á tí ìwà ìfipábanilò se pọ̀ láàrin àwọn ọmọ-ogun. Òhun náà ló sì ṣe okùnfà kí àwọn ọlọ́pàá máa dẹ́rùba àwọn obìnrin tí wọ́n bá wá fi ẹjọ́ ìwà-ipá tàbí ìfiyàjẹ́ni sùn pé àwọn kan ń halẹ̀ tàbi dúnkookò mọ́ àwọn láwùjọ. Àwọn aláṣẹ a fi dandan mú àwọn obìnrin tí wọ́n bá fi ìhónú hàn láti ṣe àyẹ̀wò ìbálé. Èyií náà ló sì fà á tí ọ̀ràn ìwà-ipá fi wọ́pọ̀ sí àwọn obìnrin tí ń gbé tàbí ṣiṣẹ́ ní tòsí ibùdó àwọn ọmọ-ogun. Wọ́n máa ń dojú ìjà kọ awọn obìnrin tí ó bá jẹ́ ajàfẹ́tọ̀ọ́ọmọnìyàn lórí ọrọ̀-ajé, ìbáraẹnigbépọ̀, ẹ̀tọ́ ẹni lábẹ́ àṣà àti ọ̀ràn tí ó bá jẹmọ́ iṣẹ́-ọba àti ìṣèlú. **Báyìi, àìsí ẹni tí ó tó láti bi àwọn arúfin yìi tàbí dá wọn lẹ́jọ́ nígbà tí wọ́n bá hùwà ìfipábánilò tàbí ìwà-ipá mìíràn síni nítorí pé a jẹ́ obìnrin ni ìpèníjà tí ó burú jùlọ tí ń kojú fífi òpin sí ìṣesí-ológun káàkiri àgbáyé.**

**2. Ìwà-ipá abẹ́lé ati ipa àwọn nǹkan ìjagun kéékéékeé:** Wàhálà ìwà-ipá abẹ́lé ti wà fún ìgbà pípẹ́. Ó pẹ́ tí àwọn ẹgbẹ́ obìnrin ti ń gbẹnusọ lórí rẹ̀. Ó sì jẹ ohun tí ó wọ́pọ̀ káàkiri gbogbo orílẹ̀-èdè lágbààyé. Ìwádìí fi hàn pé ní gbogbo ayé yìí, sàsà obìnrin ní kìí ní ìrírí ìwà-ipá láti ọwọ́ ọkúnrin tí ó jẹ́ olólùfẹ́ wọn lásìkò kan tàbí òmínràn ní ọjọ́ ayé wọn.[3] Irú ìwa-ipà báyìí tilẹ̀ máa ń sáábà la ewu lọ rékọjá níbi tí àwọn nǹkan ìjà kéékéé  (bíi ìbọn àti àdá) bá ti wà ní àrọ́wọ́tó. Ìdí ni pé wọn le lò wọ́n fún ìhàlẹ̀, ìpalára àti pípa àwọn obìnrin àti ọmọdé. **Kìí ṣe pé àwọn nǹkan ìjagun kéékèèkéé le ran ìwà-ipá sí obìnrin lọ́wọ̀ nìkan, wọn tún  máa ń jẹ́ kí ìfagbáràhàn àwọn ọkùnrin gbilẹ̀**. Irú àsìkò yòówù tí ó le jẹ́ (yálà àsìkò ogun tàbí ti àlàáfia) **ọ̀pọ ìbọn túmọ̀ sí ọ̀pọ̀ ewu fún àwọn obìnrin.** Nítorí náà, nínú ọdún yìí, a ó túbọ̀ máa ṣe àyẹ̀wò ipa tí wíwà fún títà àti pìpọ̀ si àwọn nǹkan ìjà kéékèèkéé ń ní lórí gbígbilẹ̀ ìwà-ipá sí obìnrin lápapọ̀ àti lórí ìwà-ipá abẹ́lẹ̀ ní pàtó. Bí ó tilẹ̀ jẹ́ pé ọ̀pọ àṣeyọrí bíi àtúnṣe òfin àti akitiyan ìdẹ́kun ọ̀ràn yìí ti wà, ọ̀pọ̀lọpọ̀ ẹgbẹ́ àwọn obìnrin sí ń bá iṣẹ́ lọ lórí rẹ̀ nítorí pé ó ń fẹ́ àmójútó ní kíákíá.

**3. Ìfipá-báni-lò làsìkò ogun àti lẹ́yìn ogun:** Ìṣẹ̀lẹ̀ ìfipábánilò làsìkò ogun àti lẹ́yìn ogun ń fi ìdí rẹ̀ múlẹ̀ pé wọ́n gbà pé ó jẹ́ ọ̀nà láti fi àjùlọ ìṣèlú àti ti ọkùnrin hàn. Wọ́n sì tún ń lò ó fún ìdẹ́rùbàni, ìdójútini àti ìfiyàjẹ́ni fùn àwọn obìnrin, ẹbí wọn àti àwùjọ wọn. Lóòótọ́,

pípe àkíyèsi àwọn ènìyàn sí ìwà ìrúfin yìí ń pọ̀ si láti bí ọdún díẹ̀ sẹ́yín. Síbẹ̀, **ìfipábánilò sì jẹ́ ìdíwọ́ pàkàkì fún ààbò àwọn obìnrin. Kò sì jẹ́ kí wọn le kópa nínú àjọṣepọ̀ ní áwùjọ wọn**. Ìdí ni pé ìṣẹ̀lẹ̀ yìí ń mú ìfàsẹ́yìn bá wọn nípa ti ara, ti ọkàn àti ti bìbáraẹni gbé pọ̀ ní àwùjọ. Àìṣedéédéé àti àìsí ààbo tí ó máa ń ṣẹlẹ̀ lásìkò ogun le mú kí  ìwà-ipá sí àwọn obìnrin túbọ̀ burú si. Ó sì le jẹ́ kí pípọ̀si, títànkálẹ̀ àti ìpalára ìwà náà túbọ̀ máa ga si. Kódà, lẹ́yìn 'ìfẹnukò' pé ogun ti parí, ó ṣeé ṣe kí ọ̀nà tí ìfipábánilò fi n gbilẹ̀ nínú ilé àti làwùjọ tùbọ̀ máa pọ̀ síi ju ti àtẹ̀yìnwá lọ. **Ọ̀pọ̀ ẹgbẹ́ àwọn obìnrin ni wọn ti ń tẹnu mọ ọn pé ohun tí kò ní ẹsẹ̀ nílẹ̀ rárá ni ìpèdè tí ń fi ìyàtọ̀ sí áàrin àsìkò ogun àti ìgbẹ̀yín ogun. Ara àwọn ìtọ́kasí wọn sì ni bí ìṣesí-ológun àti ìwà-ipá sí àwọn obìnrin ṣe máa ń tẹ̀ síwájú lẹ́yìn tí ìjọba bá ti kéde pé ogun ti parí.**

Ìpolongo ọlọ́jọ̀ mẹ́rìndínlógún ti ọdún yìí fún wa ní àǹfààní láti ṣe àgbéyẹ̀wò àwọn nǹkan tí àwa ajàfẹ́tọ̀ obìnrin le ṣe láti mú àwọn ìjọba dáhùn fún nńkan yìí. Yóò jẹ́ kí wọn le wa ọ́nà láti ṣe àtùnṣe sí àwọn àgbékalẹ̀ tí ń mú ìwà-ipá sí àwọn obìnrin gbilẹ̀ si.  **Bí ìṣe wa, CWGL** ń ṣe kóríyá fún àwọn ajàfẹ́tọ̀ọ́-ọmọnìyàn láti ṣe àmúlò ìpolongo ọlọ́jọ̀ mẹ́rìndínlógún yìí fún títẹjúmọ́ àwọn ìsẹ̀lẹ̀ tí ó jọ ti  agbègbè kóòwá wọn. Kíkópa nínú ìpolongo yìí kìí ṣe àǹfààní fún igbẹnusọ àti ìpàkíyèsí sí ìwà-ipá sí áwọn obìnrin nìkan. Ó tún fún wa láǹfààní láti dara pọ̀ mọ́ àwọn obìnrin orílẹ̀-èdè àti agbègbè mìíran káàkiri àgbáyé tí kò gbà fún ẹ́nikẹ́ni láti pa wọ́n lẹ́nu mọ́.  Ìdí ni pé iwà-ipá sí àwọn obìnrin jẹ́ ọ̀ràn tí ó kan gbogbo wa nì orísirísi ọ̀nà. Pẹ̀lú gbogbo nǹkan ti ń sẹ́lẹ̀, àwọn ìjọba wa ní ojúṣe láti dáhùn fún ọ̀ràn yìí, kí wọ́n fi òpin sí i, kí wọn sì pèsè aabò fún àwọn obìnrin.

## NÍPA ÌPOLONGO ỌLỌ́JỌ̀ MẸ́RÌNDÍNLÓGÚN NÁÀ.

Ìjà-fétọ̀ọ́-ẹni ọlọ́jọ̀ mẹ́rìndínlógún yìí tí a fi sọrí lílòdì sí ìwà-ipá síni nítorí pé a jẹ́ obìnrin ni ó wà fún ìpolongo kárí-ayé fún fífòpin si ìwà-ipá si obìnrin. Ibùdó Àwọn Obìnrin fún Ipò Aṣaájú ní Àgbáyé ni alàmójútó ìpolongo náà káàkiri àgbáyé. Yóò bẹ̀rẹ̀ ni ọjọ́ karùnlélógún oṣù kọkànlá tíí ṣe ọjọ́ tí a yà sọ́tọ̀ bíi Ọjọ́ Ìfòpinsí Ìwà-ipá sí àwọn Obìnrin ní Àgbáyé. Yóò sì parí ni ọjọ́ kẹwàá tíí ṣe Ọjọ́ Ẹ̀tọ́ Ọmọ-nìyàn ní Àgbáyé. A yan àwọn déètì yìí láti ṣe àtẹnumọ́ pé ìwà-ipá sí obìnrin jẹ́ ìṣelòdì sí ẹ̀tọ́ ọmọnìyàn. Ìpolongo nàá yóò yọrí sí rere nítorí ogunlọ́gọ̀ àwọn obínrin àti ọ̀pọ̀lọpọ̀ ẹlẹ́gbẹ́jẹgbé tí ń jà fún ẹ̀tọ́ obìnrin káàkiri àgbáyé. Àwọn tí wọ́n farajì fún ífòpinsí ìwà-ipá sí obìnrin.[4]

**Àpò Èròjà Àmúlò fún 2012.**

**CWGL** ń ṣe àkójọpọ̀ àwọn èròjà àmúlò fún 2012. Àwọn èròjà wọ̀nyìí yóò rán wá lọ́wọ́ nínú akitiyan wa ní àsìkò ètò ìpolongo ọlọ́jọ́ mẹ́rìndínlógún náà. Àpò náà yóò wà ní àrọ́wọ́tó ní oríṣiríṣi èdè láti oṣù kejọ. Àwọn olùkópa le rí i ní orí ìtàkùn àgbáyé wa: (http://16dayscwgl.rutgers.edu)

**Ọ̀nà àbáwọlé láti mọ̀ si:**

- Àkànṣe Ìtàkùn àgbáyé fún Ìpolongo Ọlọ́jọ́ 16 náà: http://16dayscwgl.rutgers.edu
- Ìfiwéránṣẹ́ àti ìwádìí nípa Kàlẹ́ńdà Ìpolongo lórí ìtakùn àgbáyé: http://16dayscwgl.rutgers.edu/campaign-calendar
- Fíforúkọ ẹni kún ti àwọn olùkópa nín : https://email.rutgers.edu/mailman/listinfo/16days_discussion
- Facebook: http://www.facebook.com/16DaysCampaign
- Flickr: http://www.flickr.com/photos/16dayscampaign
- Twitter: https://twitter.com/#!/CWGL_Rutgers
- 16 Days Twitter hashtag: #16days
- YouTube: http://www.youtube.com/user/CWGLRutgers
- Kọ i-meèlì sí wa nígbàkúgbà! 16days@cwgl.rutgers.edu

1.Ibùdó Àwọn Obìnrin fún Ipò Aṣaájú ní Àgbáyé ti 2011. "Àbọ̀ Ìpàde oníkọ̀jikọ̀ lórí Ìwà-ipá àti Ìṣesí-ológun sí Àwọn Obìnrin." http://cwgl.rutgers.edu/globalcenter/publications/vawmilitarism2011.pdf.
2. Ibùdó Àwọn Obìnrin fún Ipò Aṣaájú ní Àgbáyé ti 2012. "Ìjà-fẹ́tọ̀ọ́-obìnrín ọlọ́jọ̀ mẹ́rìndínlógún láti Dojú-ìjà-kọ́ Ìwà-ipá sí àwọn obìnrin: Àbájade àyẹ̀wò ìwádìí ní sókí" http://cwgl.rutgers.edu/globalcenter/publications/CWGL%2016%20Days%20Campaign%20Report%202011.pdf.
3.Àjọ Ètò-Ìlera Lágbàáyé. 2005 " Àyẹ̀wò tí Àjọ Ètò Ìlera ṣe lórí Ìwà-Ipá sí Àwọn Obìnrin: Àbájáde Àkọ́kọ́ lórí Pípọ̀, Ipá rẹ̀ àti ìṣesí Àwọn Obìnrin sí i" http://www.who.int/gender/violence/who_multicountry_study
4. 2. Ibùdó Àwọn Obìnrin fún Ipò Aṣaájú ní Àgbáyé ti 2012. "Ìjà-fẹ́tọ̀ọ́-obìnrín ọlọ́jọ̀ mẹ́rìndínlógún láti Dojú-ìjà-kọ́ Ìwà-ipá sí àwọn obìnrin: Àbájade àyẹ̀wò ìwádìí ní sókí" http://cwgl.rutgers.edu/globalcenter/publications/CWGL%2016%20Days%20Campaign%20Report%202011.pdf.